# ILÉ ALÁYỌ̀ TÍ O ṢÀFẸ́RÍ

Mary Owólabí

**ILÉ ALÁYỌ̀ TÍ O ṢÀFẸ́RÍ**
Láti ọwọ́ Diákóni Obìnrin Mary Owólabí
Copyright © 2017

**Àṣẹ tí a Kò fún ni.**
Pé a kò fún ẹnikẹ́ni láṣẹ láti tún kọ tàbí dàkọ apá kan nínú ìwé yìí ní ọ̀nàkọnà yálà nípa ẹ̀rọ ayárabíàṣá tàbí àwọn ọ̀nà mìíràn lái gba àṣẹ láti ọwọ́ ònkọ̀wé; àyàfi lílò fún bíi àkàjúwe tí ó ṣe kókó.

Gbogbo àkàjúwe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run tí a lò jẹ́ ti ìwé mímọ́ King James Version àti New Living ti Bíbélì Mímọ́.

Fún àdúrà àti ọ̀rọ̀ ìmọ̀ràn, jọ̀wọ́ pe ònkọ̀wé:
**The Divine Message and Great Mission**

**Sórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ yìí:**
+2348140606077; 07055512708

**Ẹ̀rọ ayárabíàṣá:**
thedivinemessageandgreatmissio@gmail.com

**ISBN:** 978-978-54106-7-9



ÌDÍLÉ ALÁYỌ̀ TÍ O ṢÁFẸ́RÍ

# TÁBÌLÌ ÀKÒRÍ

Ìpè Iránṣẹ́ ... ... ... ... iv
Ìfijì ... ... ... ... ... v
Ọ̀rọ̀ Àkóso ... ... ... ... vi-vii
Ìmọrírì ... ... ... ... viii-ix
Ìfáàrà ... ... ... ... x - xi
Ọ̀rọ̀ Ìsáájú ... ... ... ... xii - xiv
Ìtumọ Èdè ... ... ... ... xv-xvi

**ORÍ KÌN-ÍN-NÍ**
Ohun Àmúyẹ Rẹ ... ... ... 1 - 18

**ORÍ KEJÌ**
Ìpinnu Ọlọ́run fún Ìdílé Rẹ ... 19 - 29

**ORÍ KẸTA**
Ṣiṣẹ́ Lée Lórí ... ... ... ... 30 - 42

**ORÍ KẸRIN**
Ní Àkótán ... ... ... 43 - 45

# ÌPÈ ÌRÁNṢẸ́

"Ẹni tí Ọlọ́run pè tí ó sì rán láti dín èrò ìjọba èṣù kù ní kíkọsílẹ̀ nípa ìtọ́ni àti ìfíhàn àtọ̀runwá àti títọ́sọ́nà nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́, láti tú àṣírí tí ó n darí ẹni sí ìsọdi ọ̀mìnira àti láti sìpẹ̀ fún àti láti gba àwọn ọmọ Ọlọ́run níyànjú ní gbogbo ayé, kí á ba le jèrè wọn padà sínú ìjọba Ọlọ́run tó ga jùlọ.





# ÌFIJÌ

Mo fi iṣẹ́ ìwé yìí jì fún Ọlọ́run alàyè kanṣoṣo. Ẹni tí ó dá ọ̀run àti ayé pẹ̀lú ẹ̀kun rẹ̀ gbogbo. Òun tí ó ti jẹ́ awakọ̀ àti kẹ̀kẹ́ ìgbéyàwó mi, fún bí Ó ti ṣe jẹ́ agbára mi.

# Ọ̀RỌ̀ ÀKỌ́SỌ

Ìmísí Díákónì obìnrin Owólabí ní ṣíṣe akójọpọ̀ ìwé yìí lórí ìgbéyàwó Krístẹ́nì jẹ́ ohun tí ó dá yàtọ̀ tí ó sì jẹ́ ohun àìgbọdọ̀ má kà fún gbogbo Krítẹ́nì tòótọ́ tí ó fẹ́ ní òye ìdásílẹ̀ àtọ̀runwá náà.

Látàrí ìmọ̀ rẹ̀ tí ó gbòòrò nínú Ọlọ́run, ó ráyè mú àwọn ẹsẹ ìtanijí látinú àwọn ìwé inú bíbélì mímọ́ láti tún àkíyèsí wa pè padà sí ohun tí Ẹlẹ́dàá ní lọ́kàn tẹ́lẹ̀ nípa ìgbéyàwó.

Ìdí pàtàkì fún ìgbéyàwó ni fún ọkùnrin àti aya rẹ̀ nínú ìfẹ́ àti àjọpín ìrírí láti le ran ara wọn lọ́wọ́ láti ní ayọ̀ ayérayé nípa sísin Ọlọ́run nínú Jésù Krístì. Èkejì irú rẹ̀, ó jẹ́ ojúṣe tọkọtaya láti mú kí ìjọba Ọlọ́run ní ayé gbilẹ̀ nípa mímú àwọn ọmọ wọn dàgbà nínú ìbẹ̀rù àti ìgbọ́ràn sí Ọlọ́run.





Ìwé ìtọ́sọ́nà yìí mú kí gbogbo ohun tí ìgbéyàwó Krístẹ́nì wà fún jáde, ó sì fún ni ní àwọn ìgbésẹ̀ láti ṣe àwárí ìdùnnú nínú ìgbéyàwó. Nípa ìmísí ẹ̀mí mímọ́, Díákónì Obìnrin Owólabí ti fi kún àte àwọn ìwé kíkà Krístẹ́nì tí ó n ràn wá lọ́wọ́ láti ṣe àṣàrò àwọn ojúṣe wa gẹ́gẹ́ bí lọ́kọláya.

Kí Ọlọ́run alágbára, Ẹni tí ó dá ìgbéyàwó sílẹ̀ ran gbogbo olùka iwé yìí lọ́wọ́ láti rí ìmúṣe nínú ìgbéyàwó wọn nípasẹ̀ Jésù Krístì Olúwa wa. Àmín.

**Alàgbà Ayọ̀ Ọmọ́tádé**
Olùdarí ilé-isẹ́ Àgùnbánirò ní Ìpínlẹ̀ Delta.

# ÌMỌRÍRÌ

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ ọkọ mi ọ̀wọ́n, bàbá mi àti ọ̀rẹ́ mi, Alàgbà Julius Olúkáyọ̀dé Owólabí. Ẹyin ni adé ògo Ọlọ́run nínú ayé mi. Àtilẹyìn tòótọ́ yín, pàápàá nínú iṣẹ́ ìránṣẹ́, ní àkókò kíkọ iṣe nlá yìí jẹ́ sí ògo Ọlọ́run. Ọkọ mi, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run alágbára fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ lórí yín.

Sí ẹ̀yin ọmọ mi, mo nífẹ̀ ẹ́ yín, mo sì dúpẹ́ fún àdúróti àti ìfaradà yín.

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn òbí mi, Ọ̀gbẹ́ni àti Arábìnrin Samuel Ọlábọ̀dé Tóyè, nítorí ẹ̀yin lẹ ṣe ọlọ́kọ̀ mi wá sáyé.

Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ gbogbo àwọn bàbá mi nípa ti ẹ̀mí, tí Ọlọ́run ti lò láti tọ́jú mi; mo sọ pé kí Ọlọ́run kí ó fi èrè sí iṣẹ́ ọwọ́ yín pẹ̀lú ore-ọ̀fẹ́. Àmín.

Olùṣọ́àgùntàn àti Díákónì obìnrin S.K Agbéyangí, mi ò lè ṣe aláìdárúkọ yín nínú ìwé yìí fún bi Ọlọ́run ṣe lò yín nígbà ìmúra ìgbéyàwó wa. Àìlegbàgbé ni àwọn





ìrírí àti ẹ̀kọ́ bíbélì yín. Bàbá àti Màmá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ yín.

Olùṣọ́àgùntàn S.S Akála, mo dúpẹ̀ gidi gan lọ́wọ́ yín fún bí ẹ ti jẹ́ bàbá lótìítọ́. Mo yin Ọlọ́run fún ayé yín.

Mo dúpẹ́ bákannáà lọ́wọ́ Arábìnrin Ruth Tèmilolúwa Ọ̀rẹ́gbẹ̀san fún àdúrótì yín ní yíyọ̀nda ọkọ̀ yín fún iṣẹ́ ìwé yìí. Ọ̀gbẹ́ni Ores, ọ̀rẹ́ tí ó ṣọ̀wọ́n ni yín. Mo gbàdúrà pé Olúwa Ọlọ́run yíò pín gbogbo wa lérè, Yíò sì kà wá yẹ fún ìjọba Rẹ̀ ní orúkọ Jésù Krístì Olúwa wa.

Nkò le sàì má fi hàn, ipa ribiribi tí àwọn wọnyí kó nínú ìtumọ̀ ìwé yìí

Bro. Suyí Israel Ìbítáyò, Bro. Ayọ̀ Agbe, Sis. Fúnmi Akíntọ̀lá, Mrs. Táíwò Adéwọlé, Mr. Ogunlade Adéníyì, Mrs. Bunmi Bakare àti Mr. Similólúwa Àdùfẹ́.

Àdúrà mi ni wípé Olúwa Ọlọ́run tó ni isẹ́ rẹ̀ yíò san yín ní ẹ̀san rere fún ògo rẹ̀ nínú aiyé yín àti ìdílé yín. Àmín.

# ÌFÁÀRÀ

Ọlọ́run ṣe ìdásílẹ̀ ìgbéyàwo pé kí a le gbádùn rẹ̀, mọ rírì rẹ̀, kí á le bọ̀wọ̀ fun. Ṣùgbọ́n lónìí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbéyàwó tí ó fi ayọ̀ àti ayẹyẹ nlá bẹ̀rẹ̀ ni wọn kò ní ìgbádùn mọ́, àmọ́ ìfaradà. Àwọn aláìgbàgbọ́ tí kò rí ìkọ̀sílẹ̀ bí ẹ̀ṣẹ̀ pàápàá ti gba kámú láti wà ní ọkọ kan, aya kan pẹ̀lú ìrọ́jú nítorí ìwà ọmọlúàbí. Èyí n ṣẹlẹ̀ nítorí pé wọ́n kùnà láti mòye àwọn ìlànà tí ó wà lẹ́yìn ìgbéyàwó tí ó ní àṣeyọrí. Bí ìgbéyàwó kò tilẹ̀ sí ní abẹ́ ìdojúkọ àwọn ẹ̀mí òkùnkùn, tàbí agbára ọ̀run àpáàdì gan, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdílé ni ó wà nínú ìrírí ìpọ́njú, nítorí pé wọ́n kọ̀ láti mọ̀ àti láti tẹ̀lẹ́ àwọn ìlànà tí ó n fi àṣeyọ́rí nínú ìdílé dánilójú.

Ìgbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, a máa n sá fún òtítọ́, tàbí kí a lérò wípé àwọn ìlànà wọ̀nyí kì í ṣe òdodo inú bíbélì. Ọ̀pọ̀ sì ti ṣé àyà wọn





le láti máṣe tẹ̀lẹ́ àwọn ìlànà yìí nítorí pé yíò mú wọn dàbí ẹni tí ọtí ìfẹ́ n pa. Mo bèèrè, kí ni ó burú nínú rẹ̀ tí o bá nífẹ̀ ẹ́ olólùfẹ́ rẹ púpọ̀ jù? Òun kọ́ ha ni ìpilẹ̀ tí ìdílé rẹ yẹ kí ó dúró lé lórí bí? Èyí gan ni ohun tí o nílò fún ìdàgbàsókè ìgbéyàwó rẹ. Ó di ìgbà tí ìfẹ́ olólùfẹ́ rẹ àti ti Ọlọ́run bá n pa ọ́ bí ọtí kí o tó le ní ìdílé aláyọ̀. Ohun kan gbọ́dọ̀ máa tukọ̀ ìgbeyàwó rẹ, èyí sì ni ìfẹ́.

Ìmísí Ẹ̀mí Mímọ́ ni a fi kọ ìwé yìí láti kọ́ wa ní àwọn àṣírí tí a nílò fún ìdílé aláyọ̀ tí a yàn láàyò. Mo gbàdúrà pé Ọlọ́run alágbára yíò fi ìwé yìí ṣe ayípadà aye rẹ àti láti dá ayọ̀ òtítọ́ tí ó tọ́ sí ọ nínú ìgbéyàwó rẹ padà ní orúkọ nlá Jésù Krístì. Àmín.

# Ọ̀RỌ̀ ÌṢÁÁJÚ

Ó ti yé mi wípé ìgbéyàwó jẹ́ ohun kan tó ṣe pàtàkì sí ayé wa. Ó ṣe pàtàkì ju ìkẹ́kọ̀ọ́gboyè tàbí àmúyẹ wa, iṣẹ́, gbajúmọ̀ tàbí ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn àti oríṣiríṣi àwọn ohun mìíràn lọ. Ó sì ti wá yé mi pé, ẹni tí ó kàwé, tí ó lọ́lá, ṣùgbọ́n tí kò ní ìgbéyàwó tí ó yọrí tàbí kí ó ní ìdílé aláyọ̀, kìí ṣe aláṣeyọrí ènìyàn.

Irú ẹni bẹ́ẹ̀ kò tilẹ̀ ní ayọ̀ láti ọkàn wá, pàápàá nígbàtí gbogbo àwọn tí ó yìí ká lérò pé ó yege. Mo ti mọ̀ wípé láìní ìgbéyàwó aláyọ̀ gẹ́gẹ́bí lọ́kọláya, kò sí ayọ̀ rárá.

Ayọ̀ tí o pàdánù nínú ígbeyàwó rẹ ni ó ṣe okùnfà àìní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ayọ̀ rẹ. O lè rí ayọ̀ ìgbéyàwó rẹ gbà padà, bí ó ti wù kí o lérò wípé o ti kùnà tàbí burú tó lọ́wọ́lọ́wọ́.

**"Nítorí èyí li ọkùnrin yíò ṣe fi bàbá àti ìyá rẹ̀ sílẹ̀, òun ó sì dàpọ̀ mọ́ aya**





**rẹ̀, àwọn méjèèjì a sì di ara kan." Efésù 5:31**

Ìwọn òye ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yìí sí àwọn ẹni méjì nínú ìgbéyàwó ni ó le sọ bóyá wọn ó ni àṣeyọrí tàbí ìkùnà nínú ìgbéyàwó wọn. Ìwé mímọ́ sọ pé 'àwọn méjèèjì' tí ó túmọ̀ sí pé ènìyàn méjì yíò di ara kan. Àṣẹ ni èyí, kìí ṣe ìfẹ́ ọkàn; wípé wọn yíò di arak an, ara tí a kò lè yà sọ́tọ̀ tàbí pín níyà. A kì yíò lè rí iyàtọ́ nínú ìhùwà, iṣesí àti ìsọ̀rọ̀sí wọn, wọn ó ò máa ṣe ohun gbogbo bákan náà. Wọ́n yíò sì di ara kan.

Pẹ̀lú òye yìí, ó túmọ̀ sí pé bí ẹnìkéjì rẹ bá tilẹ̀ fẹ́ ohunkóhun yàtọ́ sí ìfẹ́ Ọlọ́run, bóyá lòdì sí ayé ara òun tìkalára rẹ̀, (tíí ṣe ara tìrẹ náà nítorí pé ẹ ti jọ jẹ́ alábàápin ara kan) tàbí lòdì sí ìdàpọ̀ yín, ìwọ ẹnìkejì gbọ́dọ̀ yára tọ Ọlọ́run tí í ṣe olùdásílẹ̀ ara kan náà lọ nínú àdúrà ìṣìpẹ̀ láti ṣe adarí ipa ọ̀nà ẹ̀yà ara tí í ṣe ẹnìkejì rẹ náà.

Tí ó bá wù ọ́ láti de ìjọba ọ̀run pẹ̀lú ẹnìkejì rẹ àti àwọn ọmọ rẹ, ó di dandan kí ó sẹ́ ojúṣe rẹ láti ṣe àwárí ìdílé tí o ṣàfẹ́rí nípa àdúrà àti ìhùwà rẹ nínú ìgbéyàwó

rẹ. Ìwọ yíò ha gé orí rẹ nítorí ẹ̀fọ́rí bí? Rárá o. Mo mọ̀ pé o kò lè ṣe bẹ́ẹ̀ , kàkà bẹ́ẹ̀, ọ̀nà àbáyọ fún ìwòsàn ni ìwọ yíò yára wá. Bákan náà, bí ohunkóhun bá n ṣe olólùfẹ́ rẹ, (tí í ẹ̀yà ara rẹ) mo lérò wípé ọ̀nà àbáyọ ni ó tọ́ kí o wá, èyí tí í ṣe Jésù, ẹni ti ó ṣẹ̀dá ìbáṣepọ̀ ẹ̀yin méjèèjì. Òun kì yíò já ọ kulẹ̀, nítorí kóò kùnà rí. Ìwọ ni o gbọ́dọ̀ sa gbogbo ipá rẹ láti ṣe ìtọ́ jú ẹ̀yà ara rẹ, ìgbéyàwó rẹ, ìbáṣepọ̀ rẹ and ìdílé rẹ nínú Krístì Jésù. Ọlọ́run yíò sì ràn ọ́ lọ́wọ́. Àmín.

Àṣeyọrí ìgbéyàwó rẹ kò níiṣe pẹ̀lú ọjọ́ orí rẹ. Ore-ọ̀fẹ́ Ọlọ́run lórí ayé rẹ àti ìgbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nìkan ló lè ṣé.

Òun (Ọlọ́run) ni ó ni ọ́, Ó nífẹ̀ rẹ, Ó sì ṣe àfẹ́rí rẹ̀ pé kí o gbádùn ìdílé aláyọ̀ nínú ìgbéyàwó rẹ. Nítorí náà, mo bẹ̀ ọ́ pé kí o tẹ̀lé E bí Ó ti n darí ipa ọ̀nà rẹ nípasẹ̀ ìwé yìí.

"Jésù sì wí fún un pé, èmi ni ọ́nà, àti òtítọ́, àti ìyè," Jn 14:6.





# ÌTUMỌ̀ ÀWỌN ÈDÈ

Ààyò ọkàn/Àfẹ́rí: Èyí jẹ́ ohun tí o fẹ́ràn láti ní.

**Ìdílé Aláyọ̀:** Èyí ni ohun tí Ọlọ́run n fẹ́ fún àyíka àti àyídà ìgbéyàwó re. Èyí jẹ́ ìgbéyàwó aláyọ̀ tí ó láṣeyọrí. Ìgbeyàwó tàbí ìbágbépọ̀ tí ó ní ìmúṣẹ.

**Àṣeyọrí:** Èyí jẹ́ ìgbàtí àwọ èròngbà rẹ bá wá sí ìmúṣẹ, ìgbà tí ó bá dé ibi tí o pinnu rẹ̀, ìgbà tí ó bá ti ní ohun tí ò n fẹ́, ìgbà tí o pinnu láti ní ohun kan tí o sì ri.

**Àkíyèsí:** Àṣeyọrí yíò wà lẹ́yìn iṣẹ́ àṣekára, èyí túmọ̀ sí pé o gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ fún àṣeyọrí rẹ. Àṣeyọrí lè wá nípa iṣẹ́ àṣekára àti ìpinnu láti ní àṣeyọrí. Ìpinnu rẹ ṣe pàtàkì nítorí pé ọ̀tá kan wà, tí í ṣe èṣù, ẹni tí kò fẹ́ kí o ṣe àṣeyọrí. Kò ní káwọ́ gbera máa wò ọ́

tìtí o ó fi ní àṣeyọrí tí o fẹ́ nínú ìgbéyàwó àti ayé rẹ. Bí o bá kọ̀ láti dá a dúró, yíò dá ọ dúró.

**Ìgbéyàwó:** Èyí ni ìdàpọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin. Ó jẹ́ àdéhùn ọkùnrin àti obìnrin láti máa gbé pọ̀ ní gbogbo ọjọ́ ayé wọn gẹ́gẹ́ bí ọkọ àti aya. Nípa òfin, o gbọ́ dọ̀ ti tójú bọ́ tàbí bàlágà (ní ti ọjọ́ orí, kí á tó lè so ọ́ pọ̀ pẹ̀lú ìyàwó). Ìgbéyàwó jẹ́ àgbékalẹ̀ Ọlọ́run, òun sì ni Olùdásílẹ̀ tí ó dàgbà jù nínú gbogbo ìdàsílẹ̀ Ẹlẹ́dàá ọ̀run òun ayé, tí í ṣe Ẹlẹ́dàá rẹ.





ORÍ KÌN-ÍN-NÍ

# OHUN ÀMÚYẸ RẸ

Njẹ́ ìwọ a í ṣe ọmọ Ọlọ́run bí? Báwo ni o ṣe yẹ láti ní ìgbéyàwó aláṣeyọrí àti ìdílé aláyọ̀? Ó jẹ́ ohun pàtàkì fún ọ pé kí o mọ ohun tí o nílò láti ní àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ; o gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọ Ọlọ́run.

Ọlọ́run dá ìgbéyàwó sílẹ̀, ìfẹ́ ọkàn Rẹ̀ sì ni wípé kí o ṣe àṣeyọrí nínú ètò ìgbéyàwó yìí. Ó ṣètò ìgbéyàwó láti mú ọ pé nípa fífún ọ ní alábàárìn, olùrànlọ́wọ́ láti tán àìní rẹ. Ó dá ìgbéyàwó sílẹ̀ látí ṣe ìfidímúlẹ̀ ìdàpọ̀ àwọn ipá méjì tí ó ti di ipá alágbára kan, èyí tí òun yíò lò láti wó àwọn ìlẹ̀kùn ọ̀run àpáàdì àti láti mú ìbísí ọ̀pọ̀ ipá nlá wá nípasẹ̀ ìdàpọ̀ wọn.

Ọlọ́run n fẹ́ kí o wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ètò wọ̀nyí. Láti wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn

ètò yìí, o gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọ Rẹ̀. Ó gbọ́dọ̀ ti di àtúnbí. Jíjẹ́ ọmọ Ọlọ́run kìí ṣe ọ̀rọ̀ ẹnu lásán, ṣùgbọ́n nípa ìgbọ́ràn rẹ. ìgbàgbọ́ rẹ, iṣẹ́ rẹ, ìdáhùnsí rẹ, ìhùwàsí rẹ àti ìwà rẹ sí ọ̀rọ̀ Rẹ̀. Àwọn wọ̀nyí ni ó mú ọ yẹ láti jẹ́ ọmọ Ọlọ́run tòótọ́.

**Mọ̀ Ọ́:** O ní láti mọ̀ Ọ́ fúnra rẹ, ó yẹ kí ó wu ìwọ tìkalárẹ láti dá a mọ̀, kò yẹ kí alárinà wà láàrin ìwọ àti Jésù Krístì Olúwa.

**Gbọ́ràn sí I Lẹ́nu:** Ó le wòsàn kí ó sì gbà ọ́ là tilétilé rẹ bí ìwọ bá le gbọ́ràn si lẹ́nu kí o sì gbẹ́kẹ̀ lé e láti tọ́ ọ sọ́nà tí o ó tọ̀ láti tún ìgbéyàwó rẹ tò. Njẹ́ ìwo ha n pa òfin rẹ̀ mọ́? Njẹ́ ò n tẹ̀lé ìdarí rẹ̀ nígbà gbogbo bí? Bí ó bá jẹ́ bẹ́ẹ̀, ìwọ sá dúró dè é, òun kì yíò já ọ kulẹ̀. Ọlọrun òtítọ́ ni òun, ìwọ sá jẹ olótiítọ́ níhà tirẹ. Ìfẹ́ Ọlọ́run kò le sàìwá sí ìmúṣẹ nínú ayé rẹ.

"Bí ẹ̀yin bá bẹ̀rù Olúwa, tí ẹ̀yin sì sìn ín, tí ẹ̀yin sì gbọ́ ohun rẹ̀, tí ẹ̀yin kò sì tàpá sí ọ̀rọ̀ Olúwa, ẹ̀yin àti ọba yín tí ó jẹ lórí yín





yíò máa wà lẹ́yìn Olúwa Ọlọ́run yín." 1Sam 12:14.

Ohun tí ó yẹ fún àkíyèsí ni wípé, o kò lè tan Ẹlẹ́dàá rẹ, Ó rí ọkàn rẹ. Ó yẹ kí o máa béèrè lọ́wọ́ Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan pé kí Ó fi ara ìwọ tìkalára rẹ hàn ọ́. Sọ fún Ọlọ́run kí Ó mọ ọ́ bí ara Rẹ̀. O léè ṣe é, yíò sì ṣé, bí o bá dúró tì Í.

## 1. ÌGBỌ́RÀN SÍ Ọ̀RỌ̀ ỌLỌ́RUN

Èyí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ohun tí ó kà ọ́ yẹ láti ní ìgbéyàwó aláṣeyọrí. Ọ̀rọ̀ Ọlọ̀run nínú ìwé Efésù 5:21

> **wípé 'Ẹ máa tẹríba fún ara yín ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run.'**

Báwo ni o ṣe n gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ ẹni tí ó ṣẹ̀dá rẹ tí ó sì tún dá ìgbéyàwó? Òun (Ọlọ́run) mọ̀ nípa gbogbo ìgbéyàwò, tirẹ kò yọ sílẹ̀. Òun ni Aṣẹ̀dá, Olùdásílẹ̀ àti Olùfilọ́lẹ̀ ìgbéyàwó. Òun ni ó mú àwọn ẹ̀yà ara (èyínì ìwọ́ àti ẹnikejì rẹ) ìgbéyàwó papọ̀,

nítorí náà, bí ohunkóhun bá ṣe àìdára nínú ìgbéyàwó rẹ, o ní láti gbẹ́kẹ̀lé é láti tọ́ ọ lórí ọ̀nà àbáyọ. Ó ti fi ọ̀rọ̀ Rẹ̀ fún ọ gẹ́gẹ́bí atọ̀ka fún ìgbéyàwo àti ìdílé aláṣeyọrí.Nítorí èyí, mo lérò wípé ó jẹ́ ohun ọlọgbọ́n láti gbọ́ràn sí I lẹ́nu fínífíní nítorí nínú ìgbọ́ràn rẹ ni ayọ̀ rẹ gbé wà. Bí ìwọ bá gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Òun yíò tan ìmọ́ lẹ̀ sí ipa ọ̀nà rẹ, o kò sì tún rìn nínú òkùnkùn àtí ìrọ́jú nínú ìgbéyàwó rẹ mọ́.

## Pàtàkì Ìgbéyàwó

Njẹ́ o mọ̀ wípé ìgbéyàwó rẹ ṣe pàtàkì púpọ̀ ju àwọn ìwé ẹ̀rí rẹ, iṣẹ́ rẹ, oko-òwò rẹ, ìgbe aye fàájì rẹ, ẹ̀kọ́ rẹ, àti bẹ́ẹ̀-bẹ́ẹ̀ lọ bí? Bí a bá lè fi irú ìpinnu, iṣe àṣekára àti ìyànláàyò tí a fún gbogbo ohun tí a ti kà síwájú yìí láti mú wọn ṣe sí ìgbéyàwó wa, aṣeyọrí yíò dájú nínú ìgbéyàwó wa. Àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ kìí ṣe ọ̀rọ̀ nípa ọjọ́ orí rẹ, bóyá o jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin tàbí owó osù rẹ; kì í ṣe ọ̀rọ̀ nípa ẹ̀yà tàbí orílẹ̀-èdè rẹ. Ṣùgbọ́n, ó jẹ́ ìwọ̀n bí ìgbéyàwó rẹ ti ṣe pàtàkì sí, tàbí jẹ ọ́ lógún





tó nínú ọkàn rẹ ju gbogbo ohun mìíràn lọ. Ìwọ ni yíò pinnu bí ìgbeyàwó rẹ ti ṣe pàtàkì sí. Àdúrà mi ni pé o kò ní ṣe àṣìyàn ìfẹ́ rẹ.

> **'Ẹ máa tẹríba fún ara yín ní ìbẹ̀rù Ọló run,'** Efésù 5:21

Ẹ ní láti tẹríba fún ara yín nínú ìrẹ̀lẹ̀, ìfẹ́, ìṣọ̀kan, nínú ẹ̀rù Ọlọ́run. Níwọ̀n ìgbà tí o bá ti gbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ àti àṣẹ Ọlọ́run yìí, o ti yege láti ní àti láti gbádùn ètò Ọlọ́run fún ìdílé rẹ.

### a. Títẹríba fún ara yín nínú ìrẹ̀lẹ̀

Ní ẹsẹ kejìlélógún orí karùn-ún ìwé Efésù, ìwé mímọ́ sọ wípé, 'ẹ̀yin aya, ẹ máa tẹríba fún àwọn ọkọ yín, gẹ́gẹ́ bí fún Olúwa.' Báwo ni o ṣe ní ìtẹríba fún ọkọ rẹ sí gẹ́gẹ́ bí aya? Ṣé ìtẹríba tìrẹ jẹ́ díẹ̀ tàbí kíkún? O kò lè gbọ́ràn sí Ọlọ́run ní ààbọ̀ kí o sì máa retí èsì.

> **Bíbélì tílẹ̀ sọ wípé'...ṣùgbọ́n agbéraga ni ó mọ̀ ní òkèrèré,'** Orin Dáfídì 138:6b.

Bí o bá gbéraga sí ọkọ rẹ, mọ̀ wípé o ti gbéraga sí Ọlọ́run pẹ̀lú, Olúwa yíò sì máa wò ọ́ láti òkèèrè. Ní àpapọ̀, títẹríba túmọ̀ sí jíjọ̀wọ́ ara ẹni fún ẹnìkan. Ìparí ẹsẹ̀ kẹjọ ìwé Pétérù kinní orí kẹta náà rọ̀ wá láti tẹríba fún ara wa nínú ìrẹ̀lẹ̀. Ọkọ àti aya, fún ara wọn, ni ó wí.

Ìrẹ̀lẹ̀ òtítọ́ rẹ sí ẹnìkejì rẹ jẹ́ ohun tí ó ṣe kókó fún ìdílé alálàáfíà. Ọ̀kan nínú àwọn ohun ìjà alágbára jùlọ tí o ní láti kíyèsára pẹ̀lú ni ìrẹ̀lẹ̀, èyí ni wípé, ìrẹ̀lẹ̀ ọkàn rẹ ni yíò mú ọ dé ibi gíga, kò sí ọ̀nà mìíràn. Ó jẹ́ ohun kòṣémánìí, ó jẹ́ dandan fún ọ láti jẹ́ onírẹ̀lẹ̀, nítorí èyí ni ìfẹ́ Ọlọrún fún ọ nínú Krístì Jésù.

O kò ní láti gbé ìgbé ayé ìgbéyàwó tìrẹ tàbí darí ílé rẹ gẹ́gẹ́bí àwọn òbí rẹ ti gbé ti wọn. Ó ṣe pàtàkì kí o mọ̀ pé, bí àwọn òbí rẹ bá ti lẹ ní ìdílé aláyọ̀ tàbí àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó wọn, o ṣì nílò ọgbọ́n Ọlọ́run láti ṣe àgbéyẹ̀wò gbogbo ohun tí o ti kọ́ pẹ̀lú òṣùwọ̀n ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Ó ṣe pàtàkì kí o mọ̀ wípé, ìgbésí ayé àwọn obí rẹ le má jẹ̀ ẹ́ bí





Ọlọ́run ṣe fẹ́ kí o gbé tìrẹ gan an , bíkòṣe bí Òun Ọlọ́run ti yàn fún ọ.

Nígbàtí ìwé mímọ́ sọ fún àwọn obìnrin pé kí wọ́n tẹríba fún ọkọ wọn, nínú ìtẹríba yìí ni ìfidímúlẹ̀ àyọ obìnrin nínú ìdílé rẹ̀ gbé wà, bẹ́ẹ̀ ni Ọlọ́run á sì mu wá sí ìmúṣe; gbogbo ìfẹ́ ọkàn obìnrin náà fún ìgbéyàwó rẹ. Gbogbo àìgbọ́ràn sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yìí jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ nlá fún obìnrin náà, tí ó sì lè fún èṣù ní àṣẹ láti jí ayọ̀ ìgbéyàwó rẹ lọ. Ìtẹríba ní kíkún ni ohun tí a paláṣẹ. Ohunkóhun tó yàtọ̀ sí èyí jẹ́ ẹ̀tàn èṣù.

Kódà kí ẹnìkejì rẹ ní ẹ̀bi tí ó hàn gbangba, o sì gbọ́dọ̀ tẹríba ní kíkún. Bí ó bá jẹ́ ìfẹ́ ọkàn rẹ ni láti ní ìdílé aláyọ̀, àfi kí o gbọ́ ràn sí àṣẹ àti ìtọ́ni Ọlọ́run, tí í ṣe Ẹlẹ́dàá rẹ àti Olùgbékalẹ̀ ìgbéyàwó ní gbogbo ọnà àti ìṣe rẹ.

**b. Títẹríba fún ara yín nínú ìfẹ́**

**'Ẹ̀yin ọkọ, ẹ fẹ́ràn àwọn aya yín, gẹ́gẹ́ bí Krístì ti fẹ́ràn ìjọ, tí ó sì fi ara rẹ fún un; Kí òun kí ó lèsọ ọ́ di mímọ́ lẹ́yìn tí a ti fi ọ̀rọ̀ wẹ̀ ẹ́ nínú agbada**

**omi. Kí òun kí ó le è mú un wá sọ́dọ̀ ara rẹ̀ bí ìjọ tí ó ní òfo láì lábàwọ́n, tàbí àléébù kan, tàbí irú nkan báwọ̀nnì; ṣùgbọ́n kí ó lè jẹ́ mímọ́ àti aláìní àbùkù. Bẹ́ẹ̀ni ó tọ́ kí àwọn ọkùnrin kí ó máa fẹ́ràn àwọn aya wọn gẹ́gẹ́ bí ara àwọn tìkarawọn. Ẹni tí ó bá fẹ́ràn aya rẹ̀, ó fẹ́ràn òun tìkararẹ̀.'** Efésù 5:25-28.

Òṣùwọn Ọlọ́run níhìn ín yìí ni pé kí ọkọ kí ó fẹ́ràn aya rẹ̀ bí Krístì ti fẹ́ràn ìjọ. Báwo ni Krístì ti ṣe fẹ́ ìjọ? Krístì fi ara rẹ̀ fún ìjọ. Àṣẹ Ọlọ́run fún ọ láti ní ìdílé aláyọ̀ ni pé kí o fi ara rẹ fún aya rẹ̀ ní gbogbo ọnà àti ìwà bí Ọlọ́run. Yálà owó rẹ ni, ara rẹ àti gbogbo ohun tí o ní, a ti paá láṣẹ fún ọ láti fi fún un nínú ìfẹ́ gẹ́gẹ́bí Krístì ti ṣe fún ìjọ. Ṣèrántí wípé ìtẹríba yìí gbọ́dọ̀ jẹ́ nínú ìfẹ́ Ọlọ́run (ẹsẹ̀ kọkànlélógún).

Lẹ́yin ìgbà tí Krístì ti fi ara rẹ̀ fún ìjọ ni ó tó yẹ ní ẹni to fọ ìjọ pẹ̀lú omi nípa ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Ó di ìgbà tí o bá fẹ́ràn aya rẹ dé o jú ikú bí Krístì ti ṣe fún ìjọ, kí ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ





tó lè ní agbára láti sọ aya rẹ di àtúnbí bí obìnrin pípé, aláìlábàwọ́n èyí tí ò n fẹ́ ni. Nítorí pé ohunkóhun tí o kò bá lè kú fún, o kò lè rà padà.

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ nínú ìwé Jòhánù kinní, orí kẹrin, ẹsẹ̀ ìkẹjọ, "ẹnití kò bá ní ìfẹ́, kò mọ Ọlọ́run, nítorí pé ìfẹ́ ni Ọlọ́run."

Nígbàtí ọkùnrin bá fẹ́ràn aya rẹ̀ nítòótọ́ àti ní ìjìnlẹ̀, Ọlọ́run ló n ṣiṣẹ́ nínú rẹ̀, nítorí pé ìfẹ́ ni Ọlọ́run. Ìdí sì nìyí tí ó fi jẹ́ ìrínṣẹ́ ìyípadà ní ọwọ́ Ọlọ́run fún aya rẹ̀.

Ìfẹ́ ìjìnlẹ̀ tí ó ní fún aya rẹ̀, tí í ṣe ẹ̀yà ara rẹ̀, yíò jẹ́ kó fọ̀ ọ́ mọ́ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Yíò sì jẹ́ mímọ́ síbẹ̀ nípa ìwẹ̀nùmọ́ yìí, èṣù kì yíò sì lè ráyè ní ẹ̀mí, ọkàn àti ara rẹ̀. Èyí yíò sì fún ọ ní ayọ̀ nínú ìbáṣepọ̀ rẹ pẹ̀lú rẹ̀. Nípa èyí, ìwọ n mú àbàwọ́n tàbí èérí àti irú nnkan bẹ́ẹ̀ kúrò nínú ìgbéyàwó rẹ (ẹsẹ̀ kẹtàdínlọ́gbọ̀n).

Bí o bá ti pinnu nítòótọ́ láti gba ayọ̀ tí èṣù ti jágbà nínú ìgbéyàwó rẹ padà, o kò gbọ́

dọ̀ tan ara rẹ jẹ. Nítorí ó ṣòro fún ọ láti fún ni ní ohun tí o kò ní. Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì kí o fi ayé rẹ fún Jésù Krístì kí o sì jọ̀wọ́ ara re fún un. Ó lè tún ọ mọ kí ó sì sọ ọ́ di pípé, òun yíò fún ọ ní aya titun, o ó sì le ṣe gẹ́gẹ́ bí ìtọ́ni rẹ̀.

Ṣe àkíyèsí pé, bí o bá ṣe jọ̀wọ́ ara rẹ fún Ọlọ́run nínú ọkàn àti àyà rẹ gẹ́gẹ́ bí ọkọ tó ni yíò sọ bí ìwọ yíò ti gbà aya rẹ padà tí yíò sì jọ̀wọ́ ọkàn rẹ̀ fún ọ ní kíkún.

Bí o kò bá tíì ṣe gbogbo ìwọ̀nyí fún ay arẹ, o kò tíì fẹ́ràn rẹ̀, èyí  ni òṣùwọ̀n Ọlọ́run. "Bẹ́ẹ̀ni ó tọ́ kí àwọn ọkùnrin kí ó máa fẹ́ràn àwọn aya wọn gẹ́gẹ́ bí ara wọn tìkalárawọn. Ẹni tí ó bá fẹ́ràn aya rẹ̀, ó fẹ́ òun tìkararẹ̀." Efésù 5:28.

Ọlọ́run mú obìnrin àti ọkùnrin papọ̀ nínú ìgbéyàwó gbogbo láti le fi ọ̀kan tún èkejì mọ, kí wọ́n sì le jùmọ̀ dára síi. Fún obìnrin, Ọlọ́run n retí pé kí ó tẹríba fún ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti fún ọkọ rẹ̀ ní kíkún kí ó lè kún ojú òsùwọ̀n gẹ́gẹ́ bí ìránṣe ìyípadà. Fún ọkùnrin ẹ̀wẹ̀, Ọlọ́run n retí pé kí ó fẹ́





Òun (Ọlọ́run) pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ̀ àti aya rẹ̀ ní ọ̀nà kannáà, kí ó lè kún ojú ọ̀sùwọ̀n gẹ́gẹ́ bí ìránṣẹ́ ìyípadà. Ohun èlò pàtàkì tí obìnrin nílò láti fi ayọ̀ àti ìdùnnú múlẹ̀ nínú ìdílé rẹ̀ ni ìtẹríba, nígbàtí ìfẹ́ jẹ́ ti ọkùnrin gẹ́gẹ́bí a ti pá láṣẹ nínú ìwé mímọ́.

O kò tíì fẹ́ràn aya rẹ, o sì n retí ìdílé aláyọ̀. Báwo? Ayọ̀ ò kìí dédé wá sínú ìdílé, o níláti ṣe àfẹ́rí rẹ̀ kí o sì ṣiṣẹ́ fún un. Kódà, o ní láti ṣiṣẹ́ takuntakun fún ayọ̀ ìgbéyàwó rẹ, o gbọ́dọ̀ ṣiṣẹ́ gbàá ni.

c. **Tìtẹríba fun ara yin nínú ìṣọ̀kan**
**A sì tún rọ̀wá láti tẹríba fún ara wa nínú ìrẹ́pọ̀ nínú ìbẹ̀rù Ọlọ́run. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wípé "Ẹni méjì le rìn pọ̀, bíkòṣe pé wọ́n rẹ́?"** Amos 3:3.

Fún ohungbogbo láti lè ṣe déédé nínú ìgbéyàwó, àti kí àlàáfíà àti ayọ̀ lè jọba, ó dára kí lọ́kọláya ní ọkàn kan nínú ohun gbogbo tí wọ́n bá n ṣe. Ìṣọ̀kan ọkàn ṣe pàtàkì.

Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àkàjúwe Jésù bí Ọkọ Ìjọ, (aya), èyí tí a lè fi wé ọkọ àti aya: a gbọ́dọ̀ ṣe àfiyé sí bí wọ́n ti n tẹríba fún ara wọn nínú ìṣọ̀kan. Kí Jésù tó fi ẹ̀mí ara rẹ̀ lélẹ̀ lórí àgbélébù fún aya rẹ (Ìjọ), ọ̀rọ̀ rẹ̀ kò yé àwọn ọmọ ẹ̀yìn àti gbogbo àwọn tí ó gbàá gbọ́. Wọn kò ní òye rẹ̀ nítorí tí a bíi nípa ti ẹ̀mí, a sì bí àwọn nípa ti ara. Wọ́n nílò àtúnbí pẹ̀lú agbára ẹ̀mí kan náà bí ìrírí Jésù kí wọn le sọ̀kan nínú ẹ̀mí, ọkàn àti ara pẹ̀lú rẹ̀. Jésù mọ̀ wípé nípa àtúnbí olùtùnú tíí ṣe Ẹ̀mí Mímọ́ nìkan ni a fi le sọ̀kan pẹ̀lú òun. Nígbà náà nìkan ni a tó le máa ríran, ronú àti láti ṣe ohun gbogbo bí tirẹ̀.

> **"Èmi ó sì béèrè lọ́wọ́ Baba, Òun ó sì fún yín ni olùtùnú mìíràn kí ó lè máa bá yin gbé títí láíláí;** 17. **Àní ẹ̀mí òtítọ́ nì; ẹnití aráyé kò le gbà nítorí kò rí i, bẹ́ẹ̀ni kò sì mọ̀ ọ́n: ṣùgbọ́n ẹ̀yín mọ̀ ọ́n, nítorí tí ó n ba yín gbé, yíò sì wà nínú yín.** 18. **Èmi kì yíò fi yín sílẹ̀ lí àìní baba, èmi ó tọ̀ yín wá.** 19. **Nígbà díẹ̀ síi, ayé kì yíò sì**





> **rí mi mọ́: ṣùgbọ́n ẹ̀yin ó ò rí mi: nítorí tí èmí wà láàyè, ẹ̀yin ó wà láàyè pẹ̀lú.** 20. **Lí ọjọ́ náà li ẹ̀yin ó mọ̀ pé, èmí wà nínú Bàbá mi, àti ẹ̀yin nínú mi, àti èmi nínú yín.** 21. **Ẹni tí ó bá ní ofin mi, tí ó bá sì n pa wọ́n mọ́, òun ni ẹni tí ó fẹ́ràn mi: ẹnití ó bá sì fẹ́ràn mi, a ó fẹ́ràn rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ Bàbá mi wá, èmi ó sì fẹ́ràn rẹ, èmi ó sì fi ara mi hàn fún un."** Jòhánù 14:16-21.

Ẹ̀mí Mímọ́ ni ó so Jésù (ọkọ ìyàwó) pọ̀ mọ́ ìjọ (ìyáwó). Nípa ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí Mímọ́, a tún ọkàn Krístì dá sínú ọkàn wa. Ah! Ìrírí ológo ni èyí jẹ́ fún ìjọ.

Bákan náà, láìsí Ẹ̀mí Mímọ́ gẹ́gẹ́bí alásopọ̀ láàrin ìwọ ọkọ àti aya rẹ, ẹ kò lè wà pápọ̀ nínú ẹ̀mí, ọkàn àti ara.

> **"Nkan wọ̀nyí ni èmí ti sọ fún yín, nígbàtí mò n ba yín gbé. Ṣùgbọ́n olùtùnú náà, Ẹ̀mí Mímọ́, ẹni tí Baba yíò rán ní orúkọ mi, òun ni yíò kọ yín ní ohun gbogbo, yíò sì ran**

**yín létí ohun gbogbo ti èmí ti sọ fún yín."** Jòhánù 14:25-26.

Èyí náà ni ìrírí ológó tí àwọn ọmọ ẹ̀yìn bá pàdé ní ọjọ́ Pẹ́ntíkọ́stì gẹ́gẹ́bí Jésù Krístì Olúwa ti ṣe ìlérí kí ó tó gòkè lo sí ọ̀run.

**"Nígbàtí ọjọ Pẹ́ntíkọ́stì sì dé, gbogbo wọn fi ọkàn kan wà níbìkan."** Ìṣe Àwọn Àpóstélì 2:1.

Àwọn tọkọtaya ní láti wà ní ọkàn kan, ní ìṣọ̀kan ọkàn ti èrò. Nígbà náà nìkan ni Ẹ̀mí Mímọ́ yíò rìi nínú ayé wọn yíò sì fi ìdí ìṣọ̀kan wọn múlẹ̀. Nígbà yìí, aya yíò wà nínú ọkọ àti ọkọ nínú aya. Àti nípa báyìí, ẹ kò ní rí àléébù tàbí àṣìṣe nínú ara yín. Gẹ́gẹ́ bí Jésù ti sọ:

**"Ìwọn kò ha gbàgbọ́ pé, Èmí wà nínú Baba, àti pé Baba wà nínú mi? Ọ̀rọ̀ tí èmí n sọ fún yín, èmi kò dáa sọ; ṣùgbọ́n Baba tí n gbé inú mi, Òun n ṣe iṣẹ́ rẹ."** Jòhánù 14:10.

Ní ọjọ́ Pẹ́ntíkọ́stì, a tú agbára sí orí àwọn ọmọ ẹ̀yìn nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́. Nígbà





míràn, àwọn ìṣòro tí à n kò lójú nínú ìgbéyàwó wa kìí ṣe nípa ìmọ̀ ohun tí ó dára nìkan, bíkòṣe agbára láti ṣe ohun tí a mọ̀ pé ó dára fún ṣíṣe.

A fún àwọn ọmọ ẹ̀yìn ní agbára láti di aya Krístì nítòótọ́ ní ọjọ́ Pẹ́ntíkọ́stì.

**"Ṣùgbọ́n ẹ̀yin ó gba agbára, nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ̀ bá bà le yín: ẹ ó sì máa ṣe ẹlẹ́rìí mi ní Jerúsálẹ́mú, àti ní gbogbo Jùdéà, àti ni Samáríà, àti títí dé òpin ilé ayé."** Ìṣe Àwọn Àpóstélì 1:8.

Ó jẹ́ ọjọ́ tí à n gba agbára nípasẹ̀ Ẹ̀mí MÍmọ́. Láìsí ìṣọ̀kan ọkàn àti èrò kan nínú ìbẹ̀rù Ọlọ́run, o kò lè rí àyè tàbí gba agbára láti ṣe àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ. Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé àṣeyọ́rí ìgbéyàwó rẹ n bẹ ní ọwọ́ rẹ nípa ìtẹríba fún ara yín nínú ìrẹ́pọ̀ àti nínú ìbẹ̀rù Ọlọ́run; kí Ẹ̀mí Mímọ́ ba lè fi ìdí ìṣọ̀kan yín múlẹ̀ nínú ẹ̀mí.

**2. Gbígbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run láti ṣe ohun tí Ó ti ṣèlérí**

Gbígbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run túmọ̀ sí gbígbáralé àti gbígbàgbọ́ nínú ọ̀rọ̀ rẹ láìṣiyèméjì. Gígbàgbọ́ pé Ó lè ṣe é àti pé yíò ṣe èyí tí Ó ti sọ nípa rẹ, ayé rẹ, ìgbéyàwó rẹ, ẹnìkejì rẹ, àwọn ọmọ rẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ó jẹ́ mímọ̀ pé Ó lè ṣe é níwọ̀n ìgbà tí Ó bá ti pinnu rẹ̀. Ó lè ṣe lọ́pọ̀lọpọ̀ ju bí a ti fi lé E lọ́wọ́. Ìwé mímọ́ wípé:

> **"Ọ̀run òun ayé yíò rékọjá, ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ mi kì yíò rékọjá."** Mat 24:35.

> **"Kò fi àìgbàgbọ́ ṣiyèméjì ìlérí Ọlọ́run; ṣùgbọ́n o le ní ìgbàgbọ́, ó n fi ògo fún Ọlọ́run,"** Rom 4:20.

Pẹ̀lú gbogbo ìwọnyìí, ó ṣe pàtàkì fún ọ láti gba ọ̀rọ̀ Ọlọ́run gẹ́gẹ́bí a ti kọ́ sínú ìwé mímọ́ gbọ́; èyí tíí ṣe bíbélì mímọ́.

Dídi ọ̀rọ̀ Ọlọ́run mú ṣinṣin: o ní láti mọ̀ pé nígbàtí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ní àyíká rẹ kò bá fún ọ ní àmì tó dára síbẹ̀, o ní láti gbẹ́kẹ̀lé é. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wípé:





> **"Kí á máa wo Jésù olùpilẹ̀ṣẹ̀ àti aláṣepé ìgbàgbọ́ wa; ẹni, nítorí ayọ̀ tí a gbé ka iwájú rẹ̀, tí ó farada àgbélébù, láìka ìtìjú sí, tí ó sì jókò ní ọwọ́ ọ̀tún ìtẹ́ Ọlọ́run."** Heb 12:2.

A ní láti

> **"...di ìjẹ́wọ́ ìrètí wa mú ṣinṣin ní àìṣiyèméjì;** (**nítorí pé olóòtọ́ ni ẹni tí ó ṣe ìlérí**)**,"** Heb 10:23.

Mú ìgbàgbọ́ rẹ lò nínú Krístì Jésù, ẹ̀rí rere kò sì ní ṣàì jẹ́ tìrẹ. Mọ̀ pé òun tí ó làná ìgbéyàwó tí ó sì wípé àwọn méjì yíò darapọ̀ wọn ó sì di ara kan, lágbára láti ṣe bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́.

Bóyá o tilẹ̀ n sọ nínú ọkàn rẹ pé, o ti ṣe ìwọ̀n tí o lè ṣé lórí gbogbo ohun tí a ti sọ ṣáájú, tí kò sì bí àṣeyọrí kankan. Mo wí fún ọ lónìí wí pé, o ní láti tẹ̀lẹ́ àwọn ìlànà wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Máṣe mọ tara rẹ nìkan tàbí ṣe ojúsàájú ní títẹ̀lẹ́ àwọn

ìdárí àti ìtọ́ni Ọlọ́run bí ó tí n darí rẹ lọ sí ibi gíga ti ìdílé aláyọ̀ àti ìgbéyàwọ́ aláṣeyọrí.

O kú oríire! Kò tíì pẹ́ jù fún ọ láti rí èrò nlá Ọlọ́run yìí gbà fún ayé àti ìgbéyàwó rẹ, nípa fífi ara rẹ sílẹ̀ àtí gbígbọ́ràn sí òfin rẹ̀, íwọ́ yíò sì gba gbogbo ohun tí í ṣe tìrẹ ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.





## ORÍ KEJÌ

# ÌPINNU ỌLỌ́RUN FÚN ÌDÍLÉ RẸ

Ohun tí Ọlọ́run n fẹ́ fún ìdílé rẹ ni ayọ̀. Ó n fẹ́ kí o ní àṣẹyọ́rí nínú ìgbéyàwó rẹ. Ìfẹ́ Rẹ̀ fún ayé rẹ ni pé kí o ní ìrírí ayọ̀ nínú ìgbéyàwó rẹ; nítorí náà, o ní láti tẹ̀lẹ́ ipa ọ̀nà Rẹ̀, kí o ba lè ní ìrírí ayọ̀ nínú ìgbéyàwó rẹ.

**Òun ni ọ̀nà, otítọ́ àtí ìyè**. Jòhánù 14:6

Ó ti fi ìyè fún ọ, ó dájú pé òun yíò dárí rẹ ní ipa ọ̀nà tí ó tọ́ láti tọ̀ ọ yíò mú ìfihàn òtítọ́ inú ọ̀rọ̀ rẹ wá fún ọ; kí ó ba lè ní ìtúsílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ àwọn ìdé ti ẹ̀mí, ara, ìhùwàsí àti ìgbéyàwó ní orúkọ nlá Jésù. Àmín. O kú oríire! Láti òní lọ, ìwọ yíò rí, o ó sì ma gbé inú òtítọ́, ìdarí àti agbára Ọlọ́run àti Olúwa wa Jésù Krístì, Àmín.

Òun ni ọkọ rẹ, Ó mọ bí ó ṣé n ṣe ọ́. Efésù 5:23.

Òun ni ohun gbogbo tí ó yẹ kí o ní, òun kì yíò sì já ọ kulẹ̀. Ó mọ̀ ọ́, Ó sì mọ̀ ọ́ láti inú ìyá rẹ wá. Jer 1:5.

> **"...ẹ fẹ́ ọmọnìkejì yín gidigidi láti ọkàn wá."** 1Pet 1:22c

Ó jẹ́ ìfẹ́ àti ohun àfẹ́rí Ọlọ́run pé kí ẹ fẹ́ràn ara yín pẹ̀lú òtítọ́ àti ọkàn tí ó mọ́. Ìfẹ́ Ọlọ́run ni pé kí o ní ìfẹ́, kí o sì fihàn nínú ìṣe rẹ sí ẹnìkejì rẹ pẹ̀lú gbogbo ọkàn rẹ.

> **"Ọ̀ṣọ́ ẹni tí kí ó máa jẹ́ ẹ̀ṣọ́ òde, ti irun dídì, àti ti wúrà lílò, tàbí ti aṣọ wíwọ̀; ṣùgbọ́n kí ó jẹ́ ti ẹni tí ó farasín lí ọkàn, nínú ọṣọ́ àìdíbàjẹ́ ti ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀ àti ẹ̀mí tútù, èyí tí ṣé iyebíye níwájú Ọlọ́run."** 1Pet 3:3-4.

Ọlọ́run n fẹ́ kí o gbẹ́kẹ̀le Òun nípa bíbọ̀wọ̀ fún ẹnìkejì rẹ, kí o fi ṣe ẹni àkọ́kọ́ lẹ́yìn Òun tí ó fi ìdí ìdásílẹ̀ ìgbéyàwó múlẹ̀.





> **"Nítorí báyìí ni àwọn obìnrin mímọ́ ìgbanì pẹ̀lú, tí wọ́n gbẹ́kẹ̀lé Ọlọ́run, fi ṣe ara wọn ní ọ̀ṣọ́, wọn a máa tẹríba fún àwọn ọkọ ti wọn."** 1Pet 3:5.

Kì í ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run pé kí o sunkún nínú ìdílé rẹ, bíkòṣe kí o máa yayọ̀ nínú Jésù. Èéṣe tí o sì n sunkún nígbà tí olùdándè rẹ n bẹ láàyè.

> **"Àti èmi, èmí mọ̀ pé Olùdándè mi mbẹ ní ààyè,..."** Job 19:25a

Ìwé mímọ́ sọ wípé:

> **"Ẹni tí ó dá mi láre wà nítòsí,"** Ísa 50:8a.

> **"Nítorí Olúwa Jèhófà yíò ràn mí lọ́wọ́ , nítorí náà èmi kì yíò dàmú; nítorí náà ni mo ṣe gbé ojú mi ró bí òkúta lílé, èmí sì mọ̀ pé ojú kì yíò tì mí."** Ìsa 50:7.

> **"Ṣùgbọ́n Olúwa mbẹ lọ́dọ̀ mi bí akọni ẹlẹ́rù, "** Jere 20:11a,

**"Bí ẹkún pẹ́ di alẹ́ kan, ṣùgbọ́n ayọ̀ nbọ̀ ní owúrọ̀."** Orin Dáfídì 30:5b.

Gẹ́gẹ́ bí ọmọ Ọlọ́run, mo fẹ́ kí o mọ̀ pé ẹ̀tọ́ rẹ ni láti ní ayọ̀ nínú ohunkóhun yówù tí ó yí ìgbéyàwó rẹ ká. Kíni ó sì n pa ọ́ lẹ́kún? Nígbà tí Ẹlẹ́dàá rẹ, Aṣẹ̀dá ọ̀run òun ayé àti ẹ̀kun rẹ̀ gbogbo, Olùdásílẹ̀ ìgbéyàwó rẹ n sọ pé kí o má sunkún —.

Òun ni ó sọ fún Hánnàh pé kó má sunkún mọ́ tí ó sì fún un ní Sámúẹ́lì àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ mìíràn, Ọlọ́run yìí kannánàn sọ fún Ábráhámù, Ó sì fún un ní Ísáákì. Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́, ìfẹ́ rẹ̀ fún ọ ni pé kí o ní ayọ̀ nínú ìdílé rẹ àti ní gbogbo ẹ̀kun ìgbéyàwó rẹ. Ó ti ṣe é tẹ́lẹ̀ rí, dájúdájú, kò ní ṣàì ṣe tìrẹ.

Njẹ́ ìwọ́ mọ̀ pé ẹ̀kún tí ò n sun jẹ́ ohun èlò lọ́wọ́ èṣù? Ó n fi ìgbéga fún àwọn ọmọlẹ́hìn rẹ̀, nítorí náà, nígbàkúgbà tí ó bá sunkún, ò n fún èṣù àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ ní okun àti agbára lórí ayé rẹ; nípa èyí, wọ́n n gba agbára sìi láti máa





ṣàkóso lórí ayé ra. Ó jẹ́ àmì àìlera àti ìjọ̀wọ́ fún ètò sàtánì.

Èéṣe tí o kò lo okun tí o fi n sunkún tí o sì n dá Ọlọ́run lẹ́bi láti máa yìn Ín, kí o sì máa jọ́sìn si I. Bí o bá le ṣe èyí lóòrèkóòrè, ìwọ yíò ri wípé ẹnu ọ̀nà ọ̀run àpáàdì àti àwọn ipá òkùnkùn tí n dún mọ̀huru mọ́ ìgbéyàwó rẹ yíò tẹríba ní ẹsẹ̀ rẹ pẹ̀lú ìrọ̀rùn.

**Ya Àwòrán Ìdílé Aláyọ̀ Tí O Ṣàfẹ́rí**

Yíò wù mí ní ìkoríta yìí, kí o yàwòrán irú ìdílé aláyọ̀ tí ọkàn rẹ ṣàfẹ́rí. Ṣe àkọsílẹ̀ bí o ti fẹ́ kí ìgbéyàwó rẹ rí, ohun tí o fẹ́ nínú ìdílé rẹ, ṣá ṣàfẹ́rí rẹ̀, kí o sì lépa rẹ̀: èyí ni pé kí o ṣiṣẹ́ le lórí, ìwọ yíò sì dé ìbẹ́ ní orúkọ nlá Jésù. Jésù Krístì Ọmọ Ọlọ́run ni ohun gbogbo tí o nílò. Òun ni Olùpèsè, Olùtùnú, Olùwòsàn, Bàbá àti Olùdámọ̀ràn. Ísa 6:9.

Ohun tí o kò bá le gbà lérò nínú ọkàn rẹ, o kò lé e ni lọ́wọ́ rẹ. Bí o bá ṣe le ríran jinlẹ̀ sí sọ púpọ̀ nípa ohun tí o jẹ́. Bí ayọ̀ àti

ìdùnnú tí ò nrí nínú ìdílé rẹ báyìí ti tó ní í ṣe pẹ̀lú irú ìdílé aláyọ̀ tí o ti gbà lérò tẹ́lẹ̀ rí.

Ó lè fún ọ ní àṣeyọ́rí nínú ìgbéyàwó rẹ kí ó sì tù ọ́ nínú ní ìhà gbogbo, nítorí pé Òun àti Ẹ̀mí Mímọ́ jẹ́ ọkan. Ó dájú pé Òun yíò tù ọ́ lára bí ìwọ́ bá jọ̀wọ́ ara rẹ fun. Yíò wo gbogbo ìròbìnújẹ́ ọkàn rẹ sàn, yíò sì tọ́jú rẹ bí baba ti n ṣe fún ọmọ rẹ̀.
Ó le ṣe jù bẹ́ẹ̀ lọ, ó tún le ṣe ju èyí tí ó béèrè lọ. Ìwọ sá dán An wò nísinsìnyìí. Kì yíò já ọ kulẹ̀ tàbí já ọ ní tànmọ́ọ̀n.

**Ṣe Àfẹ́rí Rẹ̀**

Ṣe ìlànà ohun tí o ṣàfẹ́rí láti ní gẹ́gẹ́ bí ìdílé aláyọ̀ àti ìgbéyàwó aláṣeyọrí. Bẹ́ẹ̀ní Ọ̀nà wo lo fẹ́ gbe gbà. Kọ ọ́ sílẹ̀.

- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó ngbọ́ràn.
- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó ní ìrẹ̀lẹ̀.
- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó jẹ́ olódodo.
- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó jẹ́ olótìítọ́.
- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó jẹ́ aláyọ̀.





- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó bẹ̀rù Ọlọ́run.
- Ìdílé tí ènìyàn a máa fẹ́ láti wà nígbàgbogbo àtí bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Màá fẹ́ kí o dúró díẹ̀ láti ronú jinlẹ̀ ní ìkoríta yìí. Ìwé mímọ́ sọ pé:

> **"Kí á má ṣe tàn yín jẹ, a kò lè gan Ọlọ́run: nítorí ohunkóhun tí ènìyàn bá fúrúgbìn, òun ni yíò ká."** Gal 6:7.

Ó jẹ́ ìlànà àti òṣùwọ̀n Ọlọ́run. Bí o bá gbin àìṣòótọ́, ó dájú, o kò lè ká òtítọ́ látọ̀dọ̀ ẹnìkejì rẹ àti àwọn ọmọ rẹ. Nítorí náà, gbogbo ohun tí ó n dùn ọ́ lọ́kàn láti ní, tí o sì n lálàá rẹ̀ ni o ṣeé ṣe fún ọ láti ní, bí o bá ṣàfẹ́rí rẹ̀ lótìítọ́. Mọ̀ pé bí o bá ṣàfẹ́rí rẹ̀, ó dájú pé o ó ni. Nítorí náà, gbin irúgbìn irú ìgbésí ayé àti ìwà tí o ṣàfẹ́rí nínú ọkọ àti àwọn ọmọ rẹ fúnra lára rẹ, ìwọ yío sì ní gbogbo rẹ̀. Mo ní:

- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó ngbọ́ràn.

- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó ní ìrẹ̀lẹ̀.
- Aya/ọkọ àti àwọn ọmọ tí ó jẹ́ olódodo.

Àyíká àti àyídà tí ó ní àlàáfíà nínú ìdílé, ìdílé tí ó ní àlàáfíà, ó jẹ́ àwọn ohun àìlekàtán; rántí wípé bí o bá gbin afẹ́fẹ́, ìwọ yíò ká ìjì.

> **"Nítorí wọ́n ti gbin ẹ́fúfù, wọn ó sì ká ajà..."** Hos 8:7a.

O ní láti mọ̀ pé, ìwà búburú á máa bí si lọ́ pọ̀lọlọ̀, nítorí náà, ṣọ́ra! Ìfẹ́ Ọlọ́run fún ọ ni ìdílé tí ó ní ìdùnnú, tí ó láyọ̀ àti àlàáfíà. O sì lè níi gẹ́gẹ́ bí Ó tí ṣètò rẹ̀. O kú oríire.

**Gba Ládùúrà Nípa Lílo Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run Ní Ẹnu Rẹ; Sọ Nípa Rẹ̀ Nínú Àdúrà Rẹ**

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ agbára tó n bẹ nínú ahọ́n rẹ. Agbára púpọ̀ n bẹ ní ẹnu rẹ ju bí o ti mọ̀ lọ, pàápàá nígbàtí o bá n gbàdúrà sí Ọlọ́run, ẹni tí ó dá ìgbéyàwó sílẹ̀ nípasẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì. O lè lo ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ fún ohun rere nínú àdúrà; àti





ní ọ̀nàkọnà tí o bá fẹ́ lò ó sí. O le lo àdúrà rẹ fún tàbí lòdì sí ohun yòówù tàbí ìṣẹ̀lẹ̀kíṣẹ̀lẹ̀ nínú ìgbéyàwò rẹ.

Nípasẹ̀ ọ̀rọ̀, Ọlọ́run dá ọ̀run òun ayé àti ẹ̀kun rẹ̀ gbogbo. Lò ó, lo ọ̀rọ̀ Ọlọ́rn nínú àdúrà rẹ láti dá ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí rẹ. Dá ìdílé aláyọ̀ tí ò n fẹ́ ní pẹ̀lú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nínú àdúrà: lo ọ̀rọ̀ Ọlọ́run nípasẹ̀ èyí tí a dá ìgbéyàwó sílẹ̀ láti tún ìgbéyàwó rẹ kọ́. Tún un kọ́, kí o sì tún un tò pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ; Òun ni ọ̀rọ̀ tí ó tó fún àtúntò ìdílé rẹ. Ṣe é, gbìyànjú rẹ̀, òtítọ́ ni, yíò ṣiṣẹ́, ohun tí ó ṣe é ṣe ni, ó ti ṣiṣẹ́ fún ọ̀pọ̀, ó ti ṣiṣé fún mi; ó sì dájú wípé yíò ṣiṣẹ́ fún ọ tí o bá ṣe é pẹ̀lú ìgbọràn.

Àwọn ọ̀tá àti aláyìínìke ti yàn ọ̀nà yìí kannáàn tíí ṣe ti ọ̀rọ̀, tí wọ́n sì sọ ọ̀rọ̀ ibi, ìparun, ìyapa, ìrújú, àìṣọ̀kan àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ sínú ayé rẹ, ìdílé rẹ, ìgbéyàwó rẹ, iṣẹ́ rẹ àti pàápàá, sínú ọjọ́ ọ̀la rẹ; ṣùgbọ́n mo wí fún ọ lónìí pé "o kú oríire", nítorí nípa ọ̀nà

kannáàn, o lé kọ̀ láti gbà wọ́n láàyè nípa sísọ ọ̀rọ̀ láti ẹnu rẹ ní ìbámu pẹ̀lú iwé mímọ́ tí í ṣe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà.

**"Ẹnu ni a sì fi í jẹ́wọ́ sí ìgbàlà."** Romu 10:10.

Gbàdúrà lóri àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà kí o sì ní ìgbàgbọ́ nínú Krístì Jésù bí o ti n rìn ní ìgbọràn sí ìfẹ́ àti ìdarí rẹ̀. ìwọ yíò sì rí ìdáhùn sí gbogbo ohun tí ìwọ́ ti wí.
Ó tún ṣe pàtàkì fún ọ láti ṣàkíyèsí wípé ìgbé ayé àdúrà rẹ ní n bí àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ tàbí nínú ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí. Ìwé mímọ́ wípé

**"Ejò náà sì tu omi jáde láti ẹnu rẹ̀ wá bí odò nlá sẹ́hìn obìnrin náà, kí ó lè mú kí ìṣàn omi náà gbáa lọ. Ilẹ̀ sì ran obìnrin náà lọ́wọ́, ilẹ̀ sì ya ẹnu rẹ̀, ó sì fi ìṣàn omi náà mu, tí drágónì náà tu jáde láti ẹnu rẹ̀ wá."** Ìfihàn 12:15-16.

O leè gbàdúrà, ilẹ̀ yíò sì ṣetán nígbàgbogbo láti gbé gbogbo omi, ibi, ìbànújẹ́, èdè àìyedè, ìkọ̀sílẹ̀ àti ohun





yòówù tí èṣù ti le sọ̀ sínú ìdílé tàbí ìgbéyàwó rẹ. Iṣẹ́ tìrẹ ni láti gbàdúrà láìṣàárẹ̀ gẹ́gẹ́bí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run ti paá láṣẹ fún wa. Nígbàtí o bá gbàdúrà ní gbogbo ìgbà ní orúkọ Jésù Krístì, Ọmọ Ọlọ́run, aye àti ohun gbogbo tí Ọlọ́run ti dá yíò ṣetán láti jà fún ọ. Àmín.

O gbọ́dọ̀ máa gbàdúrà fún àwọn ọmọ àti ìran rẹ pẹ̀lú.

**"Drágónì na si bínú gidigidi sí obìnrin náà, ó sì lọ bá àwọn irú ọmọ rẹ̀ ìyókù jagun, tí nwọn npa òfin Ọlọ́run mọ́, tí nwon si di ẹ̀rí Jésù mú."** Ìfihàn 12:17.

Nítori náà, o ní láti máa gbàdúrà fún ẹnikeji rẹ, àwọn ọmọ rẹ àti àwọn tí o fẹ́ràn. Mo gbàdúrà pé kí o rí ore-ọ̀fẹ́ náà gbà lónìí ní orúkọ Jésù. Àmín.

## ORÍ KẸTA

# ṢIṢẸ́ LÉE LÓRÍ

**a. Ránṣẹ́ Pe Ẹ̀mí Mímọ́**

O ní láti ṣiṣẹ́ lée lórí fúnrarẹ nípaṣẹ̀ agbára Ẹ̀mí Mímọ́. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run wípé: Nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá bà lé ọ, íwọ́ yíò gba agbára. O nílò agbára Ẹ̀mí Mímọ́ láti jẹ́ kí ó ṣeéṣe; ìgbéyàwó rẹ yíò ṣàṣeyọrí, o ó sì ní ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí bí o bá gba Ẹ̀mí Mímọ́ láàyè láti darí àti láti tọ́ ọ nígbàgbogbo. Òun yíò darí rẹ lọ́nà tó dára, sá gbọ́kàn lé E, Òun kò le ṣì ọ́ darí tàbí kí ó ṣì ọ́ lọ́nà.

Ó ṣe pàtàkì púpọ̀ kí á má ṣe kó iṣẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ kéré ní rírán wá lọ́wọ́ làti gbà àṣeyọrí fún ìgbéyàwó wa. Ìgbéyàwó tí kò ní ọwọ́ Ẹ̀mí Mímọ́ nínú kò lè ṣàṣeyọrí. Bí o bá tilẹ̀ rò pé ó n dára nísisìnyìí, ó lè wó palẹ̀ láìpẹ́ ọjọ́; èyí kìí ṣe èpè bíkòṣe òtítọ́





ọ̀rọ̀. Ìbá dára kí o gba èyí gbọ́ báyìí, kí o sì ṣiṣẹ́ lórí àṣeyọrí àti ríro ìgbéyàwọ́ rẹ lágbára nínú Krístì Jésù.

Àkókò rẹ nìyí, kí o má ba sọ ipò rẹ nú nínú ìdílé àti ìgbéyàwó rẹ. Àní, àkókò láti gba agbára Ọlọ́run alàyè sínú ayé rẹ, ilé rẹ àti ìgbéyàwó rẹ ti dé. Ẹ̀mí Mímọ́ a máa fún ni ní agbára láti tẹ̀síwájú pààpàá láàrin ogun. Ètò ìṣúná rẹ lè gbọ́ sí ọ lẹ́nu bí o bá ní agbára Ẹ̀mí Mímọ́ nínú rẹ, oko òwò rẹ náà lè di ọ̀tun bí o bá ní agbára Ẹ̀mí Mímọ́. Ìwé mimọ́ sọ pé:

> **"Ṣùgbọ́n ẹ̀yin yíò gba agbára, nígbàtí Ẹ̀mí Mímọ́ bá bà lée yín: ẹ ó sì máa ṣe ẹlẹ́rìí mi ní Jerusalem, àti ni gbogbo Judea, àti ni Samaria, àti títí dé òpin ilẹ̀ ayé."** Ìṣe Àwọn Àpóstélì 1:8.

Ẹ̀mí Mímọ́ ò lè tì ọ́ láti ṣe ibi. Nítorí náà, ìgbàkugbà tí o bá ṣebi tàbí hùwà ibi, mọ̀ pé Ẹ̀mí Mímọ́ kò sí nínú rẹ bíkòṣe ẹ̀mí èṣù. Àdúrà mi ni pé Ẹ̀mí Mímọ́ Ọlọ́run kò ní fi ọ́ sílẹ̀ lórúkọ Jésù Krístì. Àmin.

## b. Ní Ìgbàgbọ́

Ó ṣe pàtàkì láti ní ìgbàgbọ́ nínú Krístì kí ìgbéyàwó rẹ lè ṣàṣeyọrí. Ṣiṣẹ́ lórí ìgbàgbọ́ rẹ nínú Ọlọ́run, èyí tí ó le ràn ọ́ lọ́wọ́ láti rí ìrírí ìdílé aláyọ̀ tí o ṣàfẹ́rí. Ìgbàgbọ́ nínú Ọlọ́run nípaàẹ̀ Olúwa wa Jésù Krístì jẹ́ ohun kan pàtó tí o nílò láti gbé ìgbé ayé aṣẹ́gun àti idílé aláyọ̀. Ní ìdánilójú nínú Rẹ̀, Òun tí ó pè ọ́ sínú ìdàpọ̀ ìgbéyàwó. Òun náà ni ó dáa sílẹ̀ ní ìṣáájú, ìwé mímọ́ sì wípé "ohun gbogbo tí ó dá, dáradára ni". Ìwọ sá ní ìgbàgbọ́ nínú rẹ̀ wípé, Ó lè tún gbogbo àìdára àtẹ̀hìnwá inú ìdílé rẹ ṣe. Ó yẹ kí o ṣàkíyèsí ní ìkoríta yìí pé, ìwọ gẹ́gẹ́bí ẹnìkan ní láti ṣiṣẹ́ pẹ̀lú Ọlọ́run láti ṣe ilé rẹ ní ibi tí ó ṣe é gbé ní gbogbo ọ̀nà.

## d. Ìbálòpọ̀

Ó ṣe pàtàkì kí á ṣàkíyèsí wípé ìbálòpọ̀ jẹ́ ohun kòṣémánìí nínú ìgbéyàwó, láìsí rẹ̀, ìgbéyàwó rẹ lè sọ adùn rẹ̀ nù.

Àwọn tọkọtaya kan gbàgbọ́ tàbí ní èrò wípé ẹ̀ṣẹ̀ ni láti ní ìbálòpọ̀ nínú ìgbéyàwó.





Ó tọ́ kí á mọ̀ wípé ìbálòpọ̀ nínú ìgbéyàwó kìí ṣe ẹ̀ṣẹ̀, ó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìdí tí Ọlọ́run fi dá ìgbéyàwó sílẹ̀.

Ìbálòpọ̀ nínú ìgbéyàwó le jẹ́ ìgbàkugbà tí ó bá wọ̀ tí ó sì jẹ́ àjọmọ̀ àwọn ẹni méjèèjì tí í ṣe ọkọ àti aya. Ìwé mímọ́ wípé:

> **"Àwọn méjèèjì sí wà ní ìhòhò, àti ọkùnrin náà àti obìnrin rẹ̀, wọn kò sì tijú."** Gen 2:25.

Kò sí ìtíjú nínú ìbálòpọ̀ nínú ìgbéyàwó rẹ, a pọn ọ́n ní dandan fún wa kí á ri ara wa fún ara wa.

> **"Ẹ máa tẹríba fún ara yín ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run."** Efésù 5:21.

Èyí túmọ̀ sí pé ìwọ kọ́ lo ni ara rẹ bíkòṣe ẹnìkejì rẹ. O ní láti jọ̀wọ́ ara rẹ fún ẹnìkejì rẹ nígbàkúgbà tí ó bá ti béèrè, ní ìbẹ̀rù Ọlọ́run.

Màá fẹ́ sọ òkodoro ọ̀rọ̀ àti àṣírí yìí di mímọ̀ fún ọ wípé ìbálòpọ̀ pẹ̀lú ẹnìkejì rẹ lè jẹ́ àìmọye ìgbà láàrin ọ̀sẹ̀ kan bí ó bá ṣe

béèrè fún un sí. O nílò láti ṣàkíyèsí ẹnìkejì rẹ kí o sì mọ̀ bí ó ṣe ní agbára ìbálòpọ̀ sí. Bí ìwọ́ bá jẹ́ aláìlera tí o kò sì fẹ́ràn ìbálòpọ̀ pẹ̀lú ẹnìkejì rẹ, ààyè wà fún ọ láti yanjú rẹ̀ nínú àdúrà; yálà kí o gbàdúrà pé kí ẹnìkèjì rẹ̀ máṣe fẹ́ràn rẹ̀ púpọ̀ jù tàbí kí o gbàdúrà okun àti agbára fún ara rẹ làti bá ìfẹ́ ọkàn ẹnìkejì rẹ pàdé. O ní láti yan ọ̀kan.

### e. Àwọn Ọ̀rọ̀ Ẹnu Rẹ

Àwọn ọ̀rọ̀ tí ò n sọ lẹ́nu lè mú kí ẹnìkejì rẹ kí ó fẹ́ tàbí kí ó má fẹ̀ láti wà ní àyíká rẹ. Ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yíò mú kí ẹnìkejì rẹ dúró, ó yẹ kó jẹ́ ọ̀rọ̀ ìyànjú, ọ̀rọ̀ ìmoore àti ọ̀rọ̀ ìtùnú.

Ọ̀rọ̀ ẹnu lè mú kí ẹnìkejì rẹ padà wá sílé sọ́dọ̀ rẹ àti sínú ayé rẹ; ó lè mú ayọ̀ tí ó ti sọnù padà sínú ìgbéyàwó rẹ. Ó tó ìgbàwo sẹ́yìn tí o ti sọ fún ẹnìkejì rẹ wípé "má bìínú" pàápàá nígbàtí ó dá ọ lójú pé o kò lẹ́bi. Lọ́pọ̀ ìgbà, a máa n gbìyànjú láti fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé orí ẹ̀tọ́ wa la wà. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, èṣù a mú kí ẹnìkejì rẹ ṣe





àwọn ohun tí yíò mú ọ bínú; mọ̀ pé èròngbà èṣù ní àkókò bẹ́ẹ̀ jẹ́ láti da ìdílé rẹ rú, kí ó sì mú àlááfíà rẹ kúrò. Bí o ṣe lè sọ pé "má bìínú" nígbàtí o kò ṣe ohun búburú kankan tàbí ní ẹ̀bi ni yíò da àbá èṣù rú. Èyí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn àmì ìtẹríba ní kíkún fún ọkọ rẹ: èṣù lè sọ wípé òmùgọ̀ ni ọ́ láti sọ wípé "má bìínú" nígbàtí o kò jẹ̀bi, ṣùgbọ́n nítorí àlááfíà.

O kì í ṣe aṣiwèrè, ìwọ sá n rìn nínú ọgbọ́n Ọlọ́run ni. Ọ̀pọ̀ èdè àìyedè ni èṣù ti gbìn sínú ìgbéyàwó rẹ èyí tí o lè yẹ̀ nípa kíkọ́ láti lo ọ̀rọ̀ yìí "má bìínú" dáradára. Ọ̀rọ̀ kan yìí jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ohun ìjà tí ó ṣe kókó jù ní ọwọ́ rẹ láti ṣẹ́gun èṣù. Níní ìrẹ̀lẹ̀ tó bẹ́ẹ̀ láti máa sọ pé "má bìínú" nígbàkugbà tí ó yẹ, jẹ́ pàtàkì àṣírí láti gba ọkọ rẹ padà.

### e. Títọ́ Àwọn Ọmọ Yín

Àwọn ọmọ rẹ jẹ́ ẹ̀yà ara ìdílé rẹ; bí o kò bá tọ́ wọn ní ọ̀nà Ọlọ́run Ẹlẹ́dàá wọn, o lè máa ta ayọ̀ ìdílé rẹ sọnù. Báwo ni o ṣe tọ́

àwọn ẹ̀bùn ológo wọ̀nyìí (àwọn ọmọ rẹ) tí Ọlọ́run ti fi fún ọ? ìwé mímọ́ sọ wípé "ọmọ ni ìní Olúwa, ọmọ inú sì ni èrè rẹ̀," o gbọ́ dọ̀ tọ́jú ẹ̀bùn yìí ní ọ̀nà ti Krístì, èyí nì, ipa ọ̀nà òdodo.

Títọ́ tún jẹ́ mímú gbogbo ègún àti àwọn ohun mìíràn tí kò so èso tàbí tí ó le dínà àtiso èso ọmọ náà kúrò. Olúwa ti fi àwọn ẹ̀bùn yìí fún ọ láti tọ́ nípa ti ara, ìwà, àti nípa ti ẹ̀mí. Mo ti gbọ́ ti òbí kan wípé "Ha, ẹ fi wọ́n sílẹ̀, t'ayé òde òní nìyẹn," Ha! Ayé òde oní sí ègbé. Àwọn kan tilẹ̀ sọ pé "ẹ jẹ́ kí wọ́n lọ sóde ayẹyẹ nísinsìnyí nítorí nígbàtí wọ́n bá gbéyàwó, wọ́n le má rí àyè àti gbádùn ayé wọn àti láti lọ sí ilé ijó mọ́ ."

**"Tọ́ ọmọ rẹ lí ọ̀nà tí yíò tọ̀: nígbàtí ó sì dàgbà tán, kì yíò kúrò nínú rẹ̀."** Òwe 22:6.

**"Bí ọfà ti rí ní ọwọ́ alágbára, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọmọ ìgbà èwe rẹ."** Orin Dáfídì 127:4.





Irú ipa ọ̀nà tí o fi àwọn èso yìí lé àti ọ̀nà tí ò n gbà bu omi rin wọ́n nípa ti ẹ̀mí àti nípa ti ara ni yíò mú wọn dàbí ọfà ní ọwọ́ rẹ, tí yíò borí tí yíò sì gba ẹnu ọ̀nà àwọn ọ̀tá rẹ.

O ti tó àkókò fún ọ láti tún ọkàn rẹ papọ̀ láti rọ̀ mọ́ Ọlọ́run, olùfúnni ní gbogbo ọgbọ́n láti ràn ọ́ lọ́wọ́ pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀ láti so èso (àwọn ọmọ) rẹ ní ọ̀nà tìrẹ.

**f. Gba Agbára Lọ́wọ́ Àwọn Aláyìínìke Rẹ**

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé ìwọ náà yẹ kí o le jẹ́ aláyìínìke. Ó yẹ kí o ti mò báyìí pé, ìgbà tí o bá tó di aláyìínìke nípa ti ẹ̀mí fún Jésù, àwọn ọlọ́gbọ́n àrékérekè rẹ yíò gbórí sókè ju ìwọ àti gbogbo ohun tí í ṣe tìrẹ lọ. Ó dìgbà tí o bá le fi ẹ̀mí àti ọ̀rọ̀ Ọlọ́run dá àyínìpo ibi padà ní ọ̀nà kannáàn tí ó gbà wọlé sínú ohun gbogbo tó jẹ́ tìrẹ; kí o sì gba oko òwò rẹ, àwọn ọmọ rẹ àti ẹnìkejì rẹ padà, o lè má lè lu àlùyọ kí o sì ṣe àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ.

**"Nítorí pé kì í ṣe ẹ̀jẹ̀ àti ẹran ara ni àwa n bá jìjàkadì, ṣùgbọ́n àwọn ìjòyè, àwọn ọlọ́lá, àwọn aláṣẹ ibi òkùnkùn ayé yìí, àti àwọn ẹ̀mí búburú ní ojú ọ̀run."** Efésù 6:12.

Ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ pé àwọn tó ti di àyọ̀ ìdílé rẹ nígbèkùn le dàbí pé wọ́n lágbára, ṣùgbọ́n ó yẹ kí o mọ̀ wípé nítòótọ́ , o ní agbára jù wọ́n lọ ní gbogbo ọ̀nà àti nígbàkúgbà nínú Jésù Krístì. "Nítorí ẹni tí n gbé inú rẹ ju ẹni tí n gbé inú ayé lọ."

O gbọ́dọ̀ ní ìfura ti ẹ̀mí láti mọ̀ pé kìí ṣe ohun gbogbo ló n ṣẹlẹ̀ pẹ̀lú ojú lásán. O ní àríyànjiyàn kékeré pẹ̀lú ẹnìkejì rẹ, kí o tó mọ̀, o ti gbá ojú rẹ̀ o sì ti n pè é ní onírúurú orúkọ. Bí o bá lérò pé èyí ṣẹlẹ̀ lásán, a jẹ́ wípé o ti gbe gbági. Àwọn ipá òkùnkùn wà lẹ́yín irú ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú èròngbà láti tú ìdílé àti ìbáṣepọ̀ rẹ ká. O gbọ́dọ̀ kọjú ìjà sí kí o sì borí àwọn ipá ibi bẹ́ẹ̀ pẹ̀lú ìtẹríba àti àdúrà rẹ.





Yí wọn po nípa lílo ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, lòdì sí wọn nínú ayé àti ìdílé rẹ. O lè mú wíwà nínú ẹ̀mí rẹ múnádóko síi nípa kíkà àti ṣíṣàṣàrò nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run lójojúmọ́.

Nítorí náà, ó ṣe pàtàkì fún ọ láti mọ̀ àti láti ṣàkíyèsí wípé, kíkà àti ṣíṣàṣàrò nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run lóòrèkóòrè ni ohun àmúyẹ fún ọ láti ní ìdílé aláyọ̀ tí ọkàn rẹ̀ nfẹ́.

**gb. Ìkíni: Àfikún Ànfààní**

Èyí ní ṣe pẹ̀lú ìhà ilú tí o ti wá, ṣùgbọ́n lákòpọ̀, nígbà tí ọ bá jí ní òwúrọ̀ tí o sì kí ọkọ rẹ gẹ́gẹ́ bí aya, tí o sì n gbàdúrà fún un láìka ẹnikẹ́ni tó wà ní àyíká sí, o ó dá ìdílé aláyọ̀ sílẹ̀, ìwọ ó sì ní àṣeyọrí nínú ígbéyàwó rẹ.

Bákannáà, kí ọkọ máa gbàdúrà fún aya rẹ̀ lójojúmọ́ àti ní kùtùkùtù lórí ìkúnlẹ̀ rẹ̀. Sọtẹ́lẹ̀ sínú ayé rẹ̀, gbogbo ohun rere tí o fẹ́ láti rí. Ìkíni ní ṣe pẹ̀lú ẹ̀yà, àṣà àti ìhà ìlú tí o ti wá. Nípa ṣíṣe èyí, ò n dá irú

ìdílé tí ẹnu ọ̀nà àpáàdì kò lè borí sílẹ̀ nínú ẹ̀mí. Àwọn ọmọ rẹ pẹ̀lú yóò dàgbà láti tẹ̀lé ọ̀nà kannáàn tí o ti fi múlẹ̀ láti ní ìgbéyàwó aláṣeyọrí; ó dájú pé wọn yíò mú àwọn ìwà yìí látọ̀dọ̀ àwọn òbí wọn.

### i. Orúkọ Ìwúrí

Pípe ẹnìkejì rẹ ní àwọn orúkọ ìwúrí bíi ààyò ọkàn mi, ìfẹ́ mi, tèmi, ọkọ mi, oyin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, dára púpọ̀. O kò ní láti tijú láti faramọ́ àwọn ohun otítọ yì tí o n fi dánilójú láti ní ìdílé aláyọ̀, aláṣeyọrí àti ìgbádùn. Njẹ́ o tilẹ̀ ti ní ìrírí yìí rí; tí àwọn ọmọ rẹ n sọ fún ọ wípé ààyò okàn rẹ n pè ọ́ nígbàkúgbà tí ẹnìkejì rẹ bá n pè ọ́? Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, wọn a ní 'Oní tìrẹ' ti dé, 'Oyin rẹ' wà ní yàrá òkè. O leè má mọ̀, ṣùgbọ́n mo wí fún ọ lónìí pé gbogbo nkan wọ̀nyí yíò fi ojúlówó ìfẹ́ sínú àwọn ọmọ rẹ.

Àdúrà mi fún ọ lónìí ni pé kí Ọlọ́run alágbára fún ọ ní ore-ọ̀fẹ́ láti gbé ìgbésẹ̀ ìgbàgbọ́ láti rìn nínú gbogbo ohun wọ̀nyí kí o má sì ṣe fi àyànmọ́ rẹ ṣeré nípa títijú. Àmin.





### i. Bu Ọlá Fún Aya Rẹ

Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sọ wípé:

**"Bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ẹ̀yin ọkọ, ẹ máa fi òye bá àwọn aya yín gbé, ẹ máa fi ọlá fún aya, bí ohun èlò tí kò lágbára, àti pẹ̀lú bí ajùmọ̀jogún ore-ọ̀fẹ́ ìyè; kí àdúrà yí kí ó má ba ní ìdènà."** 1Pet 3:7.

Ẹ̀yin ọkọ, ẹ ni láti tẹ̀lé àti kí ẹ gbọ́ràn láìyẹsẹ̀ sí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yìí, kí àdúrà yín ma baà ní ìdènà. Fún ọ láti ní ohun tí o ṣàfẹ́rí, o gbọ́dọ̀ wó ìgbéraga rẹ palẹ̀ ní ẹsẹ̀ Kristì.

### j. Fi Ìjìnlẹ̀ Ifẹ́ Hàn

**"Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ẹ ní ìfẹ́ tí ó gbóná láàrin ara yín: nítorí ìfẹ́ ní n bo ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ mọ́lẹ̀."** 1Pet 4:8.

Bí o bá ní ojúlówó àti ìjìnlẹ̀ ìfẹ́ sí ẹnìkejì rẹ, ẹ ò ní rí púpọ̀ nínú àṣìṣe ara yín. Nígbàtí ẹ bá ti bẹ̀rẹ̀ sí ṣàròyé púpọ̀ nípa ara yín, ẹ ní láti yẹ ìpìlẹ̀ ìfẹ́ yín wò. Ohunkóhun yówù tí ó kù díẹ̀ nínú ẹnìkejì rẹ tí ó n mú ọ ṣàròyé, o lè fi síbẹ̀ pẹ̀lú

àdúrà. Nípasẹ̀ ìfẹ́ ìjìnlẹ̀ rẹ síi, ìwọ yíò di ikọ̀ lọ́wọ́ Ọlọ́run láti tún ayé ẹnìkejì rẹ mọ. Gbogbo àdúrà tí o bá gbà fún ẹnìkejì rẹ látàrí ìfẹ́ ìjìnlẹ̀, máa n lágbára láti yí ìgbésí ayé padà. Gbé e jáde, ó ṣeéṣe fún ọ láti gbádùn ìgbéyàwó rẹ àti láti ní ìdílé aláyọ̀. O kú oríire bí o ti n ṣiṣẹ́ láti ṣe àṣeyọrí nínú ìgbéyàwó rẹ.





## ORÍ KẸRIN

# NÍ ÀKÓTÁN

Jẹ́ ángẹ́lì, èyí ni ohun tí Ọlọ́run fẹ́ kí o jẹ́ fún ẹnìkejì rẹ, ọkọ, aya àti àwọn ọmọ rẹ, o ó sì ní ìdílé aláyọ̀. Mo mọ̀ dájú pé ìgbéyàwó rẹ yíò bí ìlànà tí Ọlọ́run ti là sílẹ̀, tí ó sì ti pinnu nínú ètò rẹ̀ mu, pàápàá bí o bá ṣe bẹ̀rẹ̀ sí í gbé ìgbésẹ̀ pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀ ọkàn tí o sì pinnu láti tẹ̀lé gbogbo ìlànà tí ẹ̀mí Ọlọ́run ti fi lélẹ̀ nínú ìwé yìí.

> "5. **Àti nítorí èyí náà pàápàá, ẹ má ṣe àìsimi gbogbo, ẹ fi ìwà rere kún ìgbàgbọ́, àti ìmọ̀ kún ìwà rere;** 6. **Àti ìrékọjá kún ìmọ̀, àti sùúrù kún àìrékọjá; àti ìwà-bí-Ọlọ́run;** 7. **Àti ìfẹ́ni ọmọnìkejì kún ìwà-bí-Ọlọ́run; àti ìfẹ́ni kún ìfẹ́ ọmọnìkejì.** 8. **Nítorí bí ẹ̀yin bá ní nkan wọ̀nyí tí wọ́n bá sì pọ̀,**

**wọn kì yíò jẹ́ kí ẹ ṣe ọ̀lẹ tàbí aláìléso nínú ìmọ̀ Olúwa wa Jésù Krístì.** 9. **Nítorí ẹni tí ó bá ṣe àláìní nkan wọ̀nyí, ó fọ́jú, kò lè ríran ní òkèèrè, ó sì ti gbàgbé pé a ti wẹ òun nù kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ àtijọ́.** 10. **Nítorí náà, ará, ẹ túbọ̀ máa ṣe àìsimi láti sọ ìpè àti yíyàn yín di dájúdájú: nítorí bí ẹ̀yin bá n ṣe nkan wọ̀nyí, ẹ̀yin kì yíò kọsẹ̀ láí.** 11. **Nítorí báyìí ni a ó ṣe pèsè fun yín lọ́pọ̀lọpọ̀ láti wọ ìjọba àìnípẹ̀kun ti Olúwa àti Olùgbàlà wa Jésù Krístì.** 2Pet 1:5-11.

Ìgbàgbọ́ wa gbọ́dọ̀ ju pé kí aá gbà àwọn òtítọ́ kan gbọ́ lọ; ó gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹ̀rí tí ó dúró lórí iṣẹ́ wa tí ó sì dúró lórí ìgbàgbọ́ wa. Jákọ́bù 2:14-17.

Pétérù nínú ìwé Jákọ́bù wípé:

**"Èrè kí ni ó jẹ́, ara mi, bí ẹnìkan wípé òún ní ìgbàgbọ́, ṣùgbọ́n tí kò ní iṣẹ́? Ìgbàgbọ́ nì le gbà á là bí?"** Jákọ́ bù 2:14.





Àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí kìí ṣàdédé wá, wọ́n gba iṣẹ́ àṣekára. Wọ́n kìí ṣe èyí tí a kàn sá le yàn, gbogbo wọn gbọ́dọ̀ jẹ́ ara ìgbé ayé Krístẹ́nì wa, kìí ṣe èyí tí a ó parí ọ̀kan kí á tó bẹ̀rẹ̀ òmíràn, bíkòṣe pé kí á ṣiṣẹ́ lórí gbogbo wọn lápapọ̀. Ọlọ́run n fi agbára kún wa, Ó sì n jẹ́ kí a lè ṣe ohun gbogbo, ṣùgbọ́n Òn náà ni ó n fún wa ní ojúṣe láti kẹ́kọ̀ọ́ àti láti dàgbà.

Ìgbàgbọ́ wa nínú Ọlọ́run tí ó n ràn wá lọ́ wọ́ láti ní ìdílé aláyọ̀ tí a ṣàfẹ́rí kọjá ohun tí a gbàgbọ́ nìkan; ó gbọ́dọ̀ di ara gbogbo ohun tí a ní láti ṣe láti ní ìdílé aláyọ̀ tí a ṣàfẹ́rí. Mo gbàdúrà pé kí ẹnì kọ̀ọ̀kan wa rí ore-ọ̀fẹ́ láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tí ó tọ́, kí á lè fi gbogbo ohun tí a ti kọ nínú iwé yì sí ìṣe tí yíò ràn wá lọ́wọ́ láti ní ìdílé aláyọ̀ tí a sàfẹ́rí nínú Krístì Jésù gbà ní orúkọ nlá Jésù. Àmín.